


# Ìwé ẹ̀kọ́  Ontario: Ẹ̀kọ́ ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ sáyẹ́ǹsì (SNC1W)

Ẹ̀kọ́ yií gbèrò láti ṣe ìrànlọ́wọ́ fún àwọn ọmọ ilé-ìwé láti jinlẹ̀ òye wọn lórí àwọn èrò inú ìmọ̀ ìṣẹ̀dálẹ̀, kẹ́mísítìrì, Físíkìsì àti ìmọ̀ sáyẹ́nsì ayé àti sánmọ̀, bákan náà kọ́ bí a ti ń so sáyẹ́ǹsì mọ́ ọnà ẹ̀rọ, àwùjọ àti àyíká.

| Àwọn ìrètí | Àwọn bọ́tìnì ìmọ̀ràn/àwọn èrò ńlá |
|---|---|
| **A. Àwọn ọgbọ́n sáyẹ́ǹsì, ọnà ẹ̀rọ, ìmọ̀ ẹ̀rọ  àti ìṣirò, Àwọn iṣẹ́ àti àwọn àsopọ̀.** | |
| 1. Lo àwọn ìlànà ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ sáyẹ́ǹsì àti ìlànà àpẹẹrẹ ìmọ̀ ẹ̀rọ nínú ìwádìí wọn láti ṣàgbékalẹ̀ ìjìnlẹ̀ òye ìmọ̀ sáyẹ́ǹsì tí wọ́n ń kọ́ àti láti lò àwọn ọgbọ́n ìṣẹ̀dá láti ṣe àwòṣe àwọn èrò sáyéǹsì àti àwọn ìbáṣepọ̀.<br>2. Ṣe ìtúpalẹ̀ bí àwọn èrò sáyẹ́ǹsì àti àwọn ìlànà ṣe lè di lílò ní àwọn ọ̀nà ìwúlò láti kojú àwọn ọ̀ràn-gidi ayé   àti nínú àwọn iṣẹ́ lọ́kan-ò-jọ̀kan àti ṣàpèjúwe àwọn ìlọ́wọ́sí sàyẹ́ǹsì láti ọ̀dọ̀ àwọn ènìyàn tí ó ti ní ìrírí ayé lóríṣiríṣi. | • *Ìwádìí ìjìnlẹ̀ sáyẹ́ǹsì*<br>• *Ìdánǹkanwò ìjìnlẹ̀ sáyẹ́ǹsì*<br>• *Onírú onímọ̀ ẹ̀rọ*<br>• *iṣẹ̀dá* |
| **B. Ìmọ̀ ìṣẹ̀dálẹ̀ – Ìlọ́lúpọ̀ alágbéró àti ìyípadà afẹ́fẹ́** | |
| 1. Ṣe àyẹ̀wò àwọn ipa ìyípadà afẹ́fẹ́ lórí ìdúróṣinṣin ìlọ́lúpọ̀ àti lórí oríṣiríṣi agbègbè àti ṣàpèjúwe àwọn ọ̀nà láti dínkù àwọn ipa wọ̀nyí.<br>2. Ṣe àfihàn òye ìmúdàgbà àti àjọṣepọ̀ ti àwọn agbègbè ìlọ́lúpọ̀ àti bí àwọn ìyípo ọ̀gbààyègbéwọ̀n àti agbára ṣe ń sàn nípasẹ̀ àwọn Ìlọ́lúpọ̀. | • *Àgbéró àyíkà*<br>• *Ìwọ̀ntúnwọ̀nsí ìmúdàgbà àwọn agbègbè ìlọ́lúpọ̀*<br>• *Ìyípo tí ọ̀gbààyègbéwọ̀n*<br>• *Ṣíṣàn ti agbára*<br>• *Àwọn ààyè mẹ́rin ti ayé*<br>• *Ìyípadà afẹ́fẹ́* |
| **D. Kẹ́mísítìrì – Ìṣẹ̀dá ti ọ̀gbààyègbéwọ̀n** | |
| 1. Ṣe àyẹ̀wò àwọn ipa àwùjọ, àyíká àti ètò ọrọ̀ ajé lórí lílo àwọn èròjà aláìlábùlà, àdàpọ̀ kẹ́míkà àti àwọn ọna ẹ̀rọ tí ó rí mọ.<br>2. Ṣe àfihàn òye ti ọgbààyègbẹ́wọ̀n pẹ̀lú ìlànà ti èròjà ìdìrọ̀mọ́ aláìfojúrí, àwọn ohun ìní aláìfojúrí àti ti Kẹ́míkà fún èròjà alálìlábùlà tí ó wọ́pọ̀ àti ìṣètò àwọn èròjà alaìlábùlà nínú àtẹ èròjà. | • *Àwọn èròjà ìdìrọ̀mọ́ aláìfojúrí*<br>• *Ọ̀gbààyègbéwọ̀n*<br>• *Èròjà alálìlábùlà (ètò atọ̀ọ̀mù àti àwọn àbùdá)*<br>• *Àdàpọ̀ kẹ́míkà*<br>• *Àtẹ èròjà* |
| **E. Físíkìsì – Àwọn ìlànà àti ohun èlò ti ìtànná** | |
| 1. Ṣe àyẹ̀wò àwọn ipa àwùjọ, àyíká àti ètò ọrọ̀ ajé ti ìṣelọ́pọ̀ agbára ìtànná àti ṣe àpèjúwe àwọn ọ̀nà láti ṣe àṣeyọrí lórí àwọn ìṣe alágbéró.<br>2. Ṣe àfihàn òye ti ìṣẹ̀dá àdìjọ ìtànná pẹ̀lú àwọn àbùdá mọ̀nàmọ́ná aláìsúnra àti ìsán àrá mọ̀nàmọ́ná. | • *Agbára ìtànná*<br>• *Agbára tí ó ṣe é sọdọ̀tun*<br>• *Agbára tí kìí ṣe ìsọdọ̀tun*<br>• *Ìṣe alágbéró*<br>• *Àwọn agbára ìmúnáwá*<br>• *Mọ̀nàmọ́ná aláìsúnra*<br>• *Ìsán àrá mọ̀nàmọ́ná* |
| **Ẹ. Ìmọ̀ Sáyẹ́ǹsì ayé àti sánmọ̀  – Ìwákiri sánmọ̀** | |
| 1. Ṣe ìṣirò àwọn ipa àwùjọ, àyíká àti ètò ọrọ̀ ajé ti ìwákiri sánmọ̀ àti ti àwọn ọna ẹ̀rọ tí ó wá láti ìwákiri sánmọ̀.<br>2. Ṣe àfihàn òye ti àwọn ẹ̀yà, àwọn àbùdá àti àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó sọ mi ti ètò òòrùn àti àgbáńyé àti pàtàkì sí àwọn ìlànà ní ayé. | • *Ìwákiri sánmọ̀*<br>• *Ọnà ẹ̀rọ titun*<br>• *Ètò òòrùn*<br>• *Àgbáyé, òòrùn àti ayé* |

*Ti gbà láti inú láti inú ìwé ẹ̀kọ́ ti Ontario, ipele kẹsàn án: ìmọ̀ ẹ̀kọ́ ìjìnlẹ̀ sáyẹ́ǹsì–  aláìyan ọ̀kan (2022).* https://www.dcp.edu.gov.on.ca/en/curriculum/secondary-science/courses/snc1w/strands